## Akiyesi Pataki

A fiwe yi se ikede si awọn Aṣoju iwe irohin Eleti Ọfẹ kakiri agbaiye wipe ẹnikẹni ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ranṣẹ si wa ao pe lẹjọ, ako si ni fi iwe irohin r a n ṣẹ si ẹnibẹ mọ.

# ELETI OFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

## Asayan Oro

Ewure wo alapata bi ki o ku. Awodi wo Igbin kọrọ, Kini eiye oku yio fi Igbin se ? Ori l'o nise eda l'a yaamo.

1.959

VOL. XI No. 655. LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 26/ — JANUARY 1, 1960. KOBỌ MEJI (2d)

# Keresimesi Odun De! Odun Olowo. . .

EKO. Keresimesi ọdun de ! ọdun ọlọmọ; bayi ni awọn onilu ati awọn majesin ma nkọrin ti nwọn si ma njo kakiri ni ilu Eko ninu ọdun yi Orisirisi aṣọ ala-ra-bara ati ohun meremere ni o si njade pẹlu ti awọn ọdọmọbinrin yio mura bi ọkunrin bẹnani ọdọmọkunrin paapa yio si mura bi obinrin

Oriṣi ere kareta, Egungun, Kurumo ati awọn ohun awo rẹrin bẹbẹ ni ao mari kakiri Titi l'Eko, ṣugbọn ọdun Keresimesi ọdun ni ṣe kelebọ o. Orisirisi aṣọ olowo nla ni o ti yọju sita ti awon enia si nmura bi aka ra ni odun nla

Titi ẹhingbẹti ko gba esẹ meji, Ereko ni kilo ṣubu tẹ on, Ẹhin-Ọgba, agaga. Bi awon Oyinbo Onisowo ti nlu gbanjo bẹni awon Kora paapa nkigbe oja ọdinwo, awon obinrin Onigele ati Oni Lailonu (Nylon) na mbu erin jẹ nigbati oja nwon nta.

Ki Olorun se odun na ni odun rere fun wa.

E Ku Odun
E Ku Iyedun

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated ni Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## OLOYE AWOLOWO SE ALAYE LORI ETO IJOBA

IBADAN. Oloye Awolọwọ sọ wipe, ifẹ inu gbogbo enia ni ki Dr. Asikiwe jẹ oye Prime Minister ile Nigeria awọn ẹgbẹ N.E.P.U. fẹ bẹ ẹgbẹ N.C.N.C. fẹ bẹ bẹna si ni ẹgbẹ A.G. fẹ bẹ pẹlu

Bi awọn enia ba se iranti dara-dara, nigbati mo fi sọrọ ni apejọ awọn enia aijosi, mo sọ wipe mo nlọ si igbimọ Federal ni Eko lati ṣe isẹ ti Olorun ba yan fun mi lati ọwọ awọn oludibo. ẹgbẹ A.G. si ti gba 'latigwa gẹgẹbi Alatako ninu ile igbimọ nla ti Eko.



Nigbati awọn ṣe eto ijọba ni ọjọ 20th oṣu December 1559, awọn da eto ijọba na ṣe larin awọn ẹgbẹ meji pere N.P.C ati N.C.N.C nigbati ọrọ na si ti jẹ bayi mo lero wipe awọn enia yio fẹ lati gbọ gbolohun ọrọ lẹnu mi gẹgẹbi awọn ẹgbẹ mi ti ṣe nipa rẹ.

(Wo ẹoku loju ewe kẹjọ)

# Ko Si Ere Ti Obinrin Ko Lese



Obinrin ti a nwo ninu aworan yi ni Mary Bignall, on ni a gbo wipe ko si ere ti okunrin lese, ti obinrin na ko lese o afo, o sure, o nrakoro, o si nsare. Eyi mu ki okiki re gbopkan kakiri ilu.

## Oku Olomo Gege La Ogbe

ABEOKUTA. Gbuke ni a gbo irohin iku alagba obinrin ti oruko re nje Juliana Adedoyin Oke ni Abule Elere f'agbegbe Ilori.

Ologbe iya na l'obi gbajumo Ogbeni J.A. Oke ati Olakunle Adelekan, ese awon egbe Onisowo, awon ore ati ojulumo pe sibi isinku iya na. Awon omo Olukunle bi cleda awon fi ijo mimo te gbogbo enia lorun nibi oku na.

Iya oloore na ku l'aiye sile nigbati o dagba di ogi odun merindinlogorin laiye, Ki Olorun je ki afefe rere.

## OKUNRIN KAN PA OGA RE

ABEOKUTA. A gbo irohin pe omokunrin kan ti nwon npe ni Gidado Alabi nse ise lebira lodo Abudu Ramoni Amodu. Ramoni oga re sanwo fun u, owo na wa soku sile mewa (10s) o so fun pe bi o ba di ni ojo keji, on yio ba wa owo ti o ku pa.

Gidado taku, o wipe "Owo mi ya lo gbowo mi sile-e," gegebi ara awon lonisu. Nibiti nwon gbe nsoro yi, odija tobe nigbati Gidado gbe oga re, o fi wonle, nibiyi bada ku. Kawi kafo, oga na ku ni ojo keji.

Bieto-bieto, oro na di ti awon olopa, nwon ni ki nwon ba oku na jade ki nwon si gbe lo fun ayewo ki nwon to le mo esun ti nwon o fun Gidado, sugbon lowo-lowo yi esun ojo ti nwon mba ro ni pe on lo pa Ramoni Amodu oga re nitori sile mewa.

## EWO LO FE? OGORIN BULALA TABI POUN MEJO

KADUNA. Obinrin Hausa kan ti o dara ti o si lewa lo joko t'owo t'owo niwaju Alikali, ti Alikali si mbere lowo re wipe, Awusetu? o ti 'jebi oro yi, nitorinа ewo lo fe ninu awon ijiya meteta wonyi, yala ki a na o ni ogorin bulala, tabi ki o san poun mejo tabi ki o lo si ewon osu kan?

Ese ti a gbo wipe obinrin na se ni wipe o dogungun mo soja kan, niti eke wipe, o ba obinrin kan ti oruko re nje Malama Amina lo po ninu Bareke soja ti o wa ni Panshin.

Nigbati Alikali so fun obinrin na pe ki o fi owo ara re yan eyiti o fe ninu awon iya meteta obinrin odanran na wa juwo si oko tire wipe ki o wa. O mbere lowo re pe, ewo ni ki on fi owo mu ninu awon ijiya meteta? Sugbon Alikali le oko re kuro, o si fi Awusetu si ewon osu kan


Always ask for
'DE FACTO'
the bread with the appetising flavour



HINDU SAKKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers Kawachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England



NIGERIAN TOBACCO CO. LTD.

MANUFACTURERS OF

GALLEON "NIGERIA'S FRIENDLY CIGARETTE"

SINCERE

Christmas

Greetings

AND BEST WISHES

FOR A PROSPEROUS

New Year

TO THE READERS OF THE

ELETI - OFE

# Sardauna Fe Da Ile Nigeria Si Meji



KADUNA. Sardauna Ṣokoto ti o je aṣiwaju awọn oṣelu ile Hausa so wipe on ngbero lati yọ ọwọ kuro niun iṣe'iselu ni ọdun 1961. Ṣugbọn ki on to mọwọ kuro, on fe gbogun ti awọn oṣelu ti o mbe nisalẹ odo Ọya titi on yio fi gba ilu wọn.

Nitoripe awọn ara isalẹ odo Ọya lo kokọ gbe ogun wa si Oke Ọya ni akoko idibo, nitorina on yio gbe ogun ti wọn, on yio gba ilu wọn. Lehina on yio fi aṣoju kan si isalẹ odo Ọya ti yio ma paṣẹ fun wọn on yio si tun yan aṣoju ti yio ma paṣẹ ni Oke Ọya. Bayi ni on yio da ile na si meji.

O so wipe ogun Jihadi ti baba nla on ja ku diẹ ni odun mọkanlelaadọjọ sẹhin ni isalẹ odo Ọya ni on yio tun bẹrẹ si, on yio fi eyi gbẹsan Jihadi ti awọn ara isalẹ odo Ọya gbe wa ka on mọle.

## Itan Agiliti Ati Ikoko

(APA III)

Ṣugbọn ikoko le sare ju lọ bi agilinti ti fẹ fọ wọ inu iho rẹ bẹni ikoko he e ni iru, nigbana li o wadi ajoku akata lariu ikoko ati agilinti nitoripe agilinti wa ekanna rẹ mọ inu iho rẹ fun igba pẹpẹ, ikoko si di ẹnu mọ iru agilinti ko si si ẹniti o fẹ ju ọwọ silẹ fun ẹnikan ninu awọn mejeji, ikoko ro pe gbẹgbẹhin on ni yio ka, agilinti ewẹ si ro pe iru on yio gee mọ ikoko li ẹnu.

Nikẹhin agilinti ni fun ikoko li ohun kẹlẹkẹlẹ pe "Ọrẹ mi, o rẹ mi o la ẹnu rẹ fun iṣẹju kan ki eni ba le yi oju pada eni yio si jade lati inu iho mi wa tọrọ aforijin lọwọ rẹ".

Nigbati omugọ ikoko gbọ eyi, o la ẹnu rẹ ṣugbọn agilinti ko yi oju rẹ pada rara o tubọ ra wọ inu iho rẹ lọ ni. Bo si tilẹ je pe ikoko na ihẹ ti ehin rẹ fi fẹrẹ ka, ti ekanna rẹ si fi ifẹrẹ ya, ohun ti o ri gbe ni idi rẹ wipe o gbọ ti agilinti ṣrọra nkọrin bayi wipe :-

(Wo oju-iwe keji ewe kerin)

Kere o!

A ni oriṣiriṣi ogun German to ṣeṣẹ de, fun onirurn aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road Lagos

## OLOYE L'OLA



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Tanimọwo Modilẹ ti iṣe ọmọ Ologbe Lawani, Oloye Modilẹ ti o jẹ oye ṣiwaju Salami Batula, Oloye Modilẹ ti o jalaisi ni ọjọ kẹjẹ oṣu yi ti awọn sinku rẹ ni ọjọ kejọ oṣu December, 1959.

Ọgbẹni Tanimọwo Modilẹ ti a nwo aworan rẹ yi ni a gbọ wipe awọn enia f'oju si lara pe on ni yio joye Modilẹ.

# ELETI - OFE

A-NIU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos.
P. O Box 467

CABLES & TELEGRAM
"ELETI - OFẸ LAGOS"
Phone 23370

VOL. XI NO. 655. SATURDAY DEC. 26 - JAN. 1., 1960.


## Keresimesi Odun De

Oni ni ọjọ ti a le fiwe ọjọ keji ọdun Ileya ti awọn Musulumi, eyiti awọn Yoruba ma fi npowe wipe "ọjọ kan ko dun bi ọjọ keji Ileya". Gẹgẹ bẹ ni ọjọ oni ri, ti iṣe ọjọ keji ọdun Keresimesi.

Awa Eleti-Ọfẹ fi eyi ki ẹnyin ọkawe wa nile, loko, ledo, kakiri ilẹ Nigeria ati ni ilu okere bi ilẹ Ghana, Saro ati ilu Oyinbo wipe ẹ ku ewu ọdun, ẹsi ku iyedun, ki Olodumare ṣe ọdun na ni rere fun wa.

A MERRY CHRISTMAS TO YOU ALL.

## FEDERAL ELECTIONS, 1959

### OWERRI NORTH EAST CONSTITUENCY

It is notified for general Information that the name of the successful candidate in Constituency number 298, Owerri North East, is Mr NICHOLAS UKAH and not Mr. Adolphus Mba, the name which appears in the published list of candidates for this constituency for the Federal Elections.

R. E. WRAITH, Chairman,
Federal Electoral Commission






## Awon Ojogbon Ilu Oyinbo



Eniti a nwo yi ni alagba Sir Edward Bullard, F. R. S. o je ọkan ninu awọn oṣelu tilu'Oyinbo ti nwọn dibo yan si ile igbimọ nla (House of Parliaments) iṣe ti a si gbe le lọwọ lati ma mojuto ni ki o ma ṣe alaga awọn ti o ntunpinpin nipa oju Sanma tabi nwọn ngbero lati lọ si ọrun keji.




# Awon Omo Ile Nigeria Nilu Oyinbo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni ọmọ ilẹ Nigeria to lọ bẹ ilu Scotland wo. Ẹniti o la ẹwọn gbalaja kọrun ni ọwọ ọtun ni alagba Sir Ian Johnson Gilbert, o mba awọn mẹrin sọrọ ninu awọn ọmọ agbegbe Iwọ-Orun Nigeria oruko wọn niwọnyi:-

Ọgbẹni L. E. Fagbola lo duro legbẹ Sir Johnson, Iyafin Abimbola Oaafọwọkan, ẹniti o fi ẹgbẹ ti obinrin ni Ọgbẹni P. I. Okwawa, ẹni kẹrin ni Oloye J. L. Ọmọwọrarẹ

# Afihan Nla Nilu Oyinbo




Obinrin ti a nwo ti o duro larin meji aworan yi, ni Iyafin Jean Nesbit ara adugbo kan t i

awọn nge ni Anfield nilu Liverpool. On si Hepan K. Ewey fi tabili si awọn ninu ... gbo gbona (Coffee) lori re fa lori, o si fi tayọtayọ gba.

## Gbajumo Obinrin Kan Jebi Ni Kotu

EKO. A gbọ irohin wipe obinrin gbajumọ kan lo se afọwọra lodo obinrin onisowo kan, aṣọ ti owo rẹ po to £43 lodọ Omotayo Ṣobade oro na si di eyiti awọn ngbe ara won de kotu si.

Ninu oṣu October, t o koja lọ yi ni adajọ kotu kekere ṣa konko ẹnọn osu mẹrin mọ obinrin gbajumọ na lara, ṣugbọn obinrin na sọ wipe ẹjọ ti adajọ kotu kekere na da fun on pe ki on lo si ẹwon osu mẹrin jẹ ti ara rẹ on kosi gbo eyiti o wi na. Nitorina on yio lọ si kotu ẹjọ Kotẹmilorun.

Nighati ẹjọ na dewaju adajọ Nageon de Lestangei kotu kotẹmilorun o wuye ẹjọ na lo su n o ri pe ko si ona ti enia le gba ti obinrin na ko ni jẹbi o si fa iwe ẹjọ re ya obinrin na si ni lati lo gbewa oṣu mẹrin.

Gbajumọ paapa ni obinrin ti awi yi, osi tun jẹ ọkan ninu awon Srekode ode ninyi.

## Itan Ikoko Ati Agiliti

O bere loju ewe keta

"Egungun ni pepele re,
Ere li o fi bọo,
Salobata lo fi se yeri
Ikoko ni ko ju bẹ lọ.

Bayi ni erin na di kiko fun agilinti titi ofi di oni oloni yi, bi o ba fẹ lo mu omi ni odo, ati fun ti nfi ekanna ha ilẹ ti o si nwa agilinti ti o se. bayi ni Ikoko onigberaga fi padanu gbogbo ohun ti oni ati ewa re pelu.

"IPADE WA PI OYIN O!
AMIN, AṢẸ." ODIGBA O.

# Alejo Nla Mbo Ni Nigeria



Irohin ti a sese leti fenrere wipe Alaiyeluwa Oba Obinrin ilu Oyinbo yio fi omoba obinrin ti oruko re nje Margaret ti a nwo nino aworan yi ranse wa se asoju re nigba Ominira ile Nigeria Todun 1960.

## Itan Anobi Liasu

Lati Owo Lemonu Ajakuta

Anobi Liasu je okan ninu awon omo Israel, ori oke E o eghe. Ni ojo kan, ti o je si owuro kutu-kutu o ri awon omo Israel, ti nwon towo lo si igboro Jerusalem ki awon kan ti nlo beni awon miran tun nde. Nitorina o fe lati mo kini nwon fe se lojo na. Nigbati o kiru tan o kori si igboro Jerusalem.

Nigbati o de ojude oba ori gbogbo enia ti o pe bi-be, awon to duro wa ni iduro awon to joko wa ni ijoko Anobi Liasu rora so-

galehin won o yoju wo ohun ti awon nse ninu agbo O ri orisa Baali nibiti nwon gbe ga a si, o ri oba ati awon ijoye ilu ti nse won pe samu samu, awon eiye ajo si oke ni osan gangan.

Bi Anobi Liasu ti ri gbo-gbo nkan wonyi nwon nfi ohun gbogbo rubo nwon si nfi awon omo owo se etutu pelu ibe ai ori Anobi Liasu ti gbona, gbogbo ara re si bere si gbon riri ke tile si emi o wo o ni pense imu. Nigbati oju re wale die, odide o mu opa re o bo si arin agbo o kigbe to

O wipe enyin omo Israeli

bawo ni enyin gbogbe Olorun? awon Babanla nyin Ibrahimo, Isiaka, Yakubo, Sulemon ati Dauda, ti o wa je wipe igi lasan-lasan lo ku ti enigerba fun. E wa e jeki a dan Olorun wa wo, Olorun ti a ba pe ti o ba fi ina dahun jeki a gba pe Olorun otito ni. Bi Olorun temi ba fi ina da mi lohun, ngo pa gbogbo nyin sugbon bi orisa ti nyin ba fi ina dahun ki nwon pa mi. Gbogbo won gbo enu soke lekan na wipe o wire awon si fi ojo ipade si ojo meje.

Obun ti o jeki awon enia na gba lati ba Anobi Liasu koja

(Wo yoku lojo ewe keje)

## ENITOJI BATA WEWON

KANO. Okunrin kan sun ni station Railway ni Kano, o bo bata ose re, o fi rori, o sun lo fonfon.

Omo kunrin Hausa kan ti o

nje Audu Fagge ti o nni keke Omolanke, ti o si ti nfi oju so okunrin onibata yi, ti pe onibata na sun lo.

Osunmo losi re, o bere si fa bata na diedie, o si fa yo tan, o wa ku wipe ki Audu Fagge ma ko bata na salo, ibe ni onibata na ti taji, ti o si fi gbeta o nwipe "Kai! barawo, kai! barawo," beni owo Maisanda fi te Audu ni Kasuwa. Nwon mu lo siwaju Alkali, ibe lo gbe ti gba wo ewon osu meta.

E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE

O KUN FUN IROHIN ALADUN

## OLOTU BANKI NIGERIA



Eyi ni aworan Gomina Banki, Ile ifowopamosi tile Nigeria ti Oloye Okotie-Eboh pe wa je Olotu Banki na. Orukore ni Ogbeni Roy. P. Fenton.

# Oba Obinrin Nwo Aso Yoruba



Nigbati Oba obinrin lo se abewo si ibiti a gbe nko awon obinrin ni ise owo, ni be lo gbe ba awon omo ile Yoruba meji pade ti nwon ro aso ile Yoruba. Oba na duro pelu ayo lati ma fi won se iranwo.

## NWỌN BẸ PADI MEJI LORI NILẸ KAMARUN

**ROME.** Irohin kan titi lọ de ilu Rome wipe awọn Alufa ijọ Aguda meji ni awọn onijọngbon ilẹ Kamarun bẹ lori.

A gbọ wipe awon onijọgbon na ro wọ inu Ilode Aguda nilu Bafang ni agbegbe ilẹ Faranse nilẹ Kamarun. Ara awon enia ti oro na ṣelẹ loju rẹ so wipe ninu rogbodiyan ija na Alufa ijọ Padi kan ati obinrin Padi kan fi ara gbọlọmọ.

Ilu Bafang ti a wi yi je iwon ogorun bọso silẹ Gesi. Iwe irohin kan ti a npe ni Fides so pe oruko Padi ti o ku na ni Gilles Herberle on ni Bishop ijọ na ati Padi enia dudu kan ti o njẹ Valentina Sarona Saron.

Nigbati awon enia gbe rogbodiyan wọn de nwon gbe ogun wọ ile ijo na pẹlu ibọn ati ọta.




## ITAN ANỌBI LIASU

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

ni wipe, ko nṣe oni tabi ana ni nwọn ti nfi aroye ọfọ mu ki oriṣa Baali yọ ina lẹnu. Bẹni Anobi Liasu fi wọn silẹ o si pada si ori oke, o bere si wipe Laila ilalaha. Nigbati ọjọ kẹfa ti o ti npe orukọ yi ni Ọlọrun pe e, o ni Liasu, kini o fẹ to yi Ni Anọbi Liasu ba ko gbogbo ọjọ o si ro.

Ọlọrun bere pe kilo fẹ ki Emi ṣe fun ọ Liasu dahun pe maṣe jẹki oriṣa wọn le po ina lenu re, nitori ko nṣe oni, tabi ana lo ti npọ ina jade lẹnu re. Ọlọrun si je o hen si ibere re.

Lọse ti o mbọ en mọ pe layekaye Ọlọrun ni Ọlọrun. E ma ka iwe Irohin Eleti-Ọfẹ.

E MA KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

# Ajodun Ogorun Odun Red Cross



Ngbati nwọn nṣe ajodun ọgọrun ọdun ti nwọn ti da ẹgbẹ Alanu ti Gẹsi silẹ (British Red Cross Society).

Omọba Gẹsi ni ọganjan wọn, ẹniti o de akete ti o si wọ aṣọ dudu ni Iyalin C. de Silva ara ilu Ceylon lọ ngbọwọ lọwọ ọmọba ti o fi aṣọ bo lulubi bi obinrin Musulumi.

## OLOYE MODILE D'O. LOGBE

EKO. Gbukelʼa gbọ iku Oloye Momoh Basola. Modile da Esu ni ọjọ keje oṣu 31.



awọn ti ileka re ni ọjọ kejo oṣu December, 1959 yi. lara awọn ẹbi, ọrẹ ati ojulumọ.

Ki Olorun gbe si afẹfẹ rere.

## Iya Nje N.E.P.U. Ni Oke-Oya

Sekiteri ẹgbẹ NEPU Malam Baba Tela to wa nilu Zaria kebọsi lọ ba Sir Ahmadu Bello aṣiwaju awọn Hausa, wipe ijọba ilẹ Hausa nfi iya nlanla jẹ awọn ọmọ ẹgbẹ on, nitorina ki o ṣe ikilọ fun ọmọ ẹgbẹ N.P.C. ki nwọn mase fiya jẹ ọmọ ẹgbẹ NEPU ki awọn mase fiya jẹ ọmọ ẹgbẹ N.E.P.U nitoripe a ti fi ara ṣe ọkan.

Bi awọn ọmọ N.P.C ba ti foju kan ọmọ ẹgbẹ N.E.P.U. ni awọn o ma sọko ẹebu sirawọn, aschinwa aschinbọ ogun ija ni yio bẹ silẹ. Nitorina bi awọn N.P.C. ko ba lọ dawọ duro, ao fi pẹki ko pẹki gbogbo wa na lọ mọ ija ni ija ope ni a ntiju funrawa nitoripe awọn mọ pe ija ko dọla.

OLOYE AWOLOWO ṢE ALAYE LORI ETO IJOBA
(O bere loju ewe kini)

**Ogunlọgọ awọn enia lo kọwe si mi, omiran fẹ waya, ẹlomiran si fi ẹrọ ba mi sọrọ wipe, ki njẹki ẹgbẹ A.G. parapọ pẹlu N.C.N.C ki a ba le gba ilẹ Nigeria kuro lọwọ aiye "Baba ni oki ọ".**

Nitorina mo sa gbogbo agbara mi pẹlu ọkan otitọ lati le mu ki ẹgbẹ A.G. ati N C N C parapọ gbe opo ijọba ilẹ Nigeria duro, ki a si fi Dr Asikiwe jẹ oye Prime Minister. Ohun ti a gbimoran yi le lori ni wipe ki a jẹki Middle Belt State, Mid West State ati C O R State wa, nitori ki a le da owo iya ti nwọn nfi nje awọn Hausa duro ni Oke-Oya, ki awọn na le ma jẹ idẹra ati igbadun gẹgẹbi ti awa ara isalẹ Odo-Oya, ki Dr Asikiwe jẹ oye Prime Minister. A jijọ sọrọ yi ni itunbi-inubi, o si dun mo tọtuntosi wa ki a to fi erin tuka.

Ṣamọ-ṣamọ, aṣe ọrọ yi ko dunmọ ẹgbẹ N C N C, ẹnikan ko si mọ, ayafi biri ti awọn yi ẹhin pada, ẹgbẹ A G koiti gbagbọ pe oro na ko ni jebe a si nteti lati gbọ ọrọ lati odo N C NC wa.

HOLIDAY SHOPPING

TODAY AT Bhojsons.

SUPERMARKET & COLD STORE ONLY
8.30 a.m — 1.00 p m.

PLEASE NOTE . . .

AS FROM MONDAY, 28th TILL END OF THE YEAR
WE ARE OPEN:

8.30-12.30 AND 2.00-7.00 p.m

OF COURSE . .

SUPERMARKET open till 7.00 p.m.
WITHOUT BREAK AS USUAL

Bhojsons
OYINGBO
P. O. Box 63, Ebute-Metta

For New Year Shopping




Ogun Aran ejo Inu

Aradan Worm Expeller jẹ ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buruku ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran bẹni o npa ẹyin wọn. Wa ra tire ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6
Owo ọkọ si jẹ 1/.
THE EGBA TRADING ARADAN STORES
18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2. Ebute Meta

Printed & Published The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 467 Lagos Phone